To the Chief Secretary to the Govt

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 271. SATURDAY, APRIL 21, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

**White's Radical Gonkiller.**

:o:

(NATIVE.)

*[A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.]*

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

*[Fun Atọsi lailai ati litun.]*

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa criṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Jakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, kọ si nję ki o ri aye wu arun mi silẹ.

LAGOS 1928

"AWA O MA JO, AWA O MA YO, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—
No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gaslamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (I'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

**Are you a Mechanic ?**—If so you m want Tools, now or so

**Do you intend to put up a house ?** Then you will require Builder's Hardwa

In either case you cannot do be than call at

***B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores***

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and pri to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

***J. C. VAUGHAN***

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fu awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati o nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kan

Owo Ogbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Ata Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ng kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi Ọja ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremerẹtibẹ.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

EWU LỌ LORI RẸ, EWU LỌ, YE!!!

Fifojudi ti ọkọnrin kan fi oju di mọto jẹlẹnkẹ kan ni Opopo-nla *(Broad Street)* ni Satide ijẹjọ fẹrẹ sọ ẹran ara ọkọnrin na di bakaya apapandodo; bi mọto ti mbọ lati Ita Tinubu, bẹni ọkọnrin yi ṣe eti gbọin si fere "Dakun'ya fun" ti awamọto yi nfọn, ti o si sare kọja oju Titi, gẹrẹ bi o ti ni ki on bọ si apa keji ọna, afara bẹni mọto amunimada yi gbe soke ti o si jũ si odi keji. Korobata ti ọkọnrin yi na'lẹ mu ki o fi ẹnu tu'lẹ bi Turukũ, şiba ni awọn enia pe bõ, şugbọn o ṣe orire pe ko fi ara pa nibi kọkan. Ha! ha!! ha!!! ti awọn enia ṣe mu ki ogboni yi gbera, rẹrẹ o si şiyan ko duro gb'ọbẹ.

IBADAN ỌMỌ AJ'ORO SUN.

A gbọ pe ni iwọn ọsẹ melo sẹhin, ojo kan ti o rọ ni Ibadan rọ Yinyin pẹlu; Yinyin ni ọgbẹ ilẹ! Eyi ara!!!

Ẹ KU EWU O!

Ẹru ko şai ba ẹnikẹni lọjọ ọsẹ nigbati okiki kan wa pe igi iyeye ti o mbẹ ni ọja Ita Faji leti ile Gbadamọsi Bishi wo lojiji ti o si ya lọ ba waya manamana: ẹsẹkẹsẹ o di bi o lọ ya mi, obinrin ri ejo o ni on o sa, o daju pe ara iku lo nya a.

Igi na ja waya pupọ tobẹ ti gbogbo ina ti o mbẹ lorere adugbo na ko fi le tan, şugbọn lọjọ keji rẹ, awọn "Meriwo" ti da bo o, nwọn si ti parọ gbogbo jamba ti igi na fi kọlu awọn waya, ki Ọlọrun ma jẹ a rin lọjọ ebi np'ọna, a si fi eyi ki gbogbo awọn ara adugbo na nwọn ku ewu, gẹgebi o ti jẹ pe ẹda Ọlọrun kan ko wu ewu lọjọ na—*Alhamdu Li Lahi.*

## OLOGBE JOSIAH DOHERTY.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Ọrọ diẹ ni a fẹ sọ nipa Ologbe Josiah H. Doherty gẹgẹ bi a ti sọ asọtẹlẹ rẹ ni ọsẹ to kọja.

Ọrọ pupọ ni Iwe-irohin ti sọ nipa iku rẹ, ọpọlọpọ enia lo si ndaro rẹ, bi a ti nkọwe lọwọ yi, gbogbo ọrọ ti awọn Iwe-irohin si nsọ nipa rẹ, lo si nfun enia ni ẹkọ ati ọgbọn pẹlu.

Lai si tabi-tabi oku kan ti şiwaju oku Akanni, ki işe Josiah H. Doherty nikan lo kọkọ ku ni ilẹ yi bẹni ki işe on nikan li yio si jẹ ẹniti o lọ jẹ ipe Ọlọrun ni ilẹ yi lati inu *Januray* ti a ti bọ si inu ọdun 1928, bi o ti wu ki o ri, ẹgbagbeje enia ti kọja, ogọrọ ọmọ-enia mbẹ lọwọlọwọ yi ti o şẹşẹ npọka iku, a ko le şẹşẹ ma sọ ti awọn ẹniti nwọn ndi ni aşọ funfun nisisiyi lati kan mọ posi ati lati lọ gbe gbin.

Njẹ ti o ba jẹ bayi, ẹ ha şe ti o jẹ wipe iku ti Josiah H. Doherty ni olukuluku nmu sọ, ti nwọn si ndaro iku rẹ titi di bi a ti nwi yi?

Ọpọlọpọ awọn ẹniti o ti rekọja bi irẹ nwọn ko gbajumọ ni tabi nwọn ko ni owo to Doherty? bi a tilẹ ri ọpọlọpọ ẹniti o le sọ wipe owo Doherty bu a ya o le gongo, a ko le şai fẹ ku ninu awọn ẹniti o mbẹ ni ilẹ yi loni tabi ti o ti rekọja lọ si *Alikiyaomọ* ti Ọlọrun ko şe fun, ko kan pin dogba.

Ati pẹlu a le ri ninu olowo bi irẹ ti ti o lọ si *Alikiyaomọ* lai sọ nipa awọn ẹniti o si nmi loke epẹ ki lo şe ti a ko fi le daro wọn to bẹ? iwa olukuluku lo ndamu rẹ.

Nigbati Doherty ku gbogbo ilu bẹrẹ si sọro rẹ ni rere, a ko i ti gbọ buburu rẹ lẹnu ẹnikan, tọmọde-tagba ni onile ati alejo, ẹniti o şe fun ati ẹniti ko şe fun, gbogbo wọn ni nwọn bẹrẹ si rohin rẹ ni rere.

Awọn apakan tilẹ fi Doherty we Ologbe Alaji Alli Fahm ẹniti o lọ jẹ ipe Ọlọrun ni ọjọ 21 oşu *November* ọdun 1923, pe a fi iku rẹ lo tun dun gbogbo enia julọ, bi iku Alaji ti a wi yi ti jẹ ohun edun fun ọpọlọpọ enia, kini ha njẹ bẹ, awọn Yoruba ni iwa rere lẹşọ enia, iwa rere lo

ntọ ni si ọna tara, lẹhin iku ọlaji Fahm, iku Doherty li a tun le fi we ara wọn ninu awọn olowo ti o ku ni ilẹ yi lẹnu titun yi.

Iwa ! iwa !! iwa !!! ki lo ha nję iwa ? ki iṣe wipe ki enia ma fi ajẹ tabi ọpa wa 'kọ, bẹni ki iṣe ki enia ma fi ada wa 'lẹ.

Ẹniti o ni owo ti ko le fi ṣe rere fun enia, ti ko le lawọ fun aya, ọmọ ati obi ko ni iwa, ẹniti o lowo lọwọ ti ko le fi ṣe ilu rẹ ni rere ko ni iwa, ẹniti o si ni dukiya ti ko le fi mọ aladugbo ko ni iwa, ẹniti o ni owo lọwọ ti ko le fi bọ talaka ko ni iwa, ẹniti owo mbẹ lọwọ rẹ ti ọmọ ẹnikeji rẹ si sunkun lọ ba a pe idamu de si on, ko bo on laşiri ti o si ni aiyafibi ti o ba le ri ohun idogo mu wa ki on ya ni owo-ele (interest) ko ni iwa arara.

Ogidileje Kiriyo ati Imale lo mbẹ ni ilu Eko yi loni ti nwọn lowo lọwọ daradara ti nwọn ko le fi ṣe gbogbo ohun ti a sọ wọnyi, ewo ni o lẹ ṣe ẹtọ ati ẹyẹ bi Doherty ninu wọn ?

Ki lo ṣe ti nwọn ko fi le ṣe bi irẹ ?—tabi ki lo ṣe ti nwọn ko fi le kọ iṣe rẹ ati awọn ẹniti ata'a gbogbo ti nwọn ti fi owo wọn tẹ ilu lọrun ni sanmoni wọn ?

Idahun rẹ ni pe arankan, tẹmbẹlẹkun, ifẹ ara ẹni nikan, imunibini ati irẹ awọn ohun buburu bẹ-bẹ ni ko le jẹ ki nwọn le ṣe e.

Nwọn bi Ologbe Josiah H. Doherty ninu oṣu August ọdun 1866—ọdun kejile-lọgọta ninu ọdun yi, nigbati o di ọjọ Satide ọjọ 24 oşu March to kọja yi lo fi wa silẹ lọ si ọdọ Oluwa rẹ.

Gbogbo ilu gbọjikan pẹlu ariwo ẹkun ati idaro pe Doherty olore lọ, ha ! oṣe ! awọn ko ri olore awọn mọ, gbogbo awọn ẹniti o nkẹdun iku rẹ, ti ko ba si okun ti o nṣe fun wọn, nwọn ko le bikita ẹduniku rẹ, gẹgẹbi a ti sọ lẹhin pe oku kan ti ṣ'waju oku Akanni ani aimọye enia ti ṣiwaju Doherty lọ, ti aja ko gbọ ti ẹran ko mọ, ti nwọn tilẹ ti gbe ẹlomiran de itẹ "*Bury*", ki ẹlomiran to ṣẹṣẹ gbọ, ki işe ti talika, bẹni ki işe ti aini owo, iwa olukuluku lo ndamu rẹ—a ko sọrọ nipa enia ti o ni lati ku ni ilu, a sọrọ nipa awọn enia nla ti mbẹ ni ilu, ti o tọ ki ilu kẹdun iku rẹ ki nwọn si ṣe ọfọ rẹ pẹlu, ṣugbọn iwa buruku wọn ha jẹ ki eyi le jẹ bẹ ? agbẹdọ !

Tani ki a sọ wipe ki o wa daro wọn aja ni tabi ẹran lai sọ ti awọn ara ilu *Awuzu bi lahi*, ki Ọlọrun ko fi Jimọ ti o ni Alamisi.

Tagba-tọmọde, ọkunrin ati obinrin onile ati alejo, wukuwuku ati Kẹmberi ati awọn ọmọ *ka wo ngan ni* lo ba wọn sin oku rẹ lọ si itẹ lọjọ ọsẹ ọjọ keji ti o sinmi ninu lasigbo aiye wa yi.

O ku o pẹlu iwa rẹ ninu sare loni, ti o ba jẹ wipe iwa rere bi awọn ẹlomiran gẹgẹbi a ti rohin rẹ yi lo nhu yio ma ri loni ẹwẹ ti o ba si jẹ wipe iwa buburu ti awọn ẹlomiran nhu ninu gbogbo igbesi-aiye wọn lo nhu, yio ma ri lọhun, takada iṣẹ olukuluku gba-gba-gba ni nwọn ma gbe le e lọwọ lọjọ *Alikiyaomo* pẹlu ibere bi igbati nwọn ba ma bere ọrọ lowọ alufin ni Kotu ni ni apẹrẹ ti aiye.

Anu ṣe wa lati sọ wipe ko si ẹniti ko mọ wipe ile-aiye ki iṣe a-wa 'lọ a fi ẹniti o ba npurọ tan ara rẹ jẹ patapata lo le wipe ko si ọjọ-idajọ, nwọn mọ wipe *la şaku fihiu* aiye lọja ọrun ni ile, ẹwẹ nwọn si mọ gbangba wipe iwa ti olukuluku ba hu nigbesi-aiye rẹ lo ma ba ni *Qiyaomat*, iyẹn ko i pada titi lọ de *Zemguru*, bẹni yio si ri titi ọjọ Ajinde, *Bibeli* ati *Quran* kọ wa bẹ.

Aye ko i si fun wa nisisiyi lati sọrọ nipa igbesi aiye rẹ, nigbati aye ba dilẹ fun wa, a o tọro gafara lọwọ Meigida mi lati yọda ojule ti yio tẹ mi lọrun daradara lọwọ rẹ, ṣugbọn loni, a fẹ ba ilu kẹdun iku rẹ.

Ki iṣe wipe ilu lo bẹ wa lọwẹ lati ba awọn kẹdun iku Josiah H. Doherty awa li a fẹ kẹdun ikun rẹ fun ilu gẹgẹbi o ti jẹ oku ti o wọ ọpọlọpọ enia lara ni ilu, ati lati fa ọrọ diẹ yọ sode larin rẹ, lati fi kọgbọn ati ẹkọ—ọrọ wa ko pọ tobẹ loni

Nitorina a ki awọn, ọmọ-olok, ilu, ọrẹ, alabaṣọ, alafọranlọ, olubori rẹ ni ilu nwọn ku ọfọ Josiah H. Doherty, ki Ọlọrun fi inu rere han a, gẹgẹbi o ti jẹ wipe enia kole wa ni aiye lai ni alebu tirẹ arara, ohunkohun ti o ba jẹ ohun ibi ti o ṣe, ki Ọlọrun fi alubarika inu rere rẹ darijin i, ki o si gbe si afẹfẹ rere—amin.

## IMỌRAN FUN AWỌN ỌMỌ-OLOKU

O yẹ ki a gba awọn ọmọ-oloku ni imọran kekere kan eyiti a si ro wipe yio ṣe wọn lanfani, lẹhin iku baba wọn.

Ni igbati a o fi gbọ ti iku Josiah H. Doherty, awọn ọmọ rẹ mẹta. Lọya meji ati Dokita kan lo tufọ iku baba wọn, dajudaju Ọlọrun fi ọmọ jinki Doherty, a si ro wipe ti nwọn ba ni ki nwọn to oruko gbogbo wọn sinu iwe-ọfọ baba wọn, a ro wipe aye ko le to ninu takada eyiyi ni *Obituary*, ṣugbọn ohun ti awọn mẹta ṣe ni gbogbo wọn ṣe awọn mẹtẹta na ni a si fẹ gba ni imọran gẹgẹbi owe kan ti o sọ wipe, ẹiyẹ Akoko ni ki on to pẹhinda ọmọ on yio to igi sọ.

Nigbati Doherty ku, ọpọlọpọ enia lo nwoye bawo ni Doherty ti ṣe fẹ ki ẹhin rẹ ri, gẹgẹbi o ti jẹ wipe ẹniti o ba ti jẹ onişowo *Merchant* pataki ni ilu, ti o ba si papoda bayi, işẹ tabi owo rẹ agbara kaka lo fi nlọ, ati pẹlu ọpọlọpọ onişowo bẹ lo ti lọ ni ilẹ yi ti ko lọjọ gbọrọ ti owo wọn parẹ, ṣugbọn nigbati nwọn ka iwe-ogun ati bi gbogbo nkan yio ti ṣe le ma lọ letoleto, ọkan ọpọlọpọ balẹ, a ko le ṣẹṣẹ sọ ti awọn ẹniti o jẹ onilara-owo rẹ.

Gẹgẹbi ọro ti Doherty fi sẹhin a ri dajudaju pe o nfẹ ki ẹhin on dara, ki o fẹrẹ le dara ju igbati on tikalararẹ mbẹ ninu *Duniyan* ti gbogbo enia fi npe e ni Ọga papa lọ.

Ẹ mura gidigidi ki ẹ ṣe gẹgẹ bi ifẹ baba nyin, banuso, ma ba enia sọ enia ko si mọ aiye ti di eke, ẹ mu ara nyin lọkan, ẹ maṣe jẹ ki awọn aṣitani ati abilisi ri aye ko si arin nyin, ẹ maṣe jẹ ki ẹnikẹni kọ nyin lẹkọ, lotọ Aṣitani ti Ọlọrun ti pese ina-eleru silẹ de mbẹ, Aṣitani ọmọ Anabi Adamọ si mbẹ pẹlu, ṣugbọn Aṣitani ọmọ araiye lo buru julọ.

Nitorina ẹ ṣe ara nyin lọkan, ẹ ma fi ero ara nyin lu ero, nipa bayi gbogbo nkan yio ma lọ letoleto ẹwẹ ki yio si jẹ ki orukọ baba nyin le parun, gbogbo ilu ki yio si le gbagbe ore ti baba nyin nṣe bọrọ.

Nigbati Doherty mbẹ niu Duniyan, o jẹ ẹnikan ti o fẹran ilu yi pupọ, ti ko si gba ẹnikẹni laye olẹ ati tẹmbẹlẹkun ati irufẹ bẹ-bẹ ti ko tọ fun ọmọluwabi, bi o ti jẹ wipe ni igba kan ti nwọn koko fara tẹmbẹlẹkun eyiti o si nja ranin-ranin nilẹ lọwọlọwọ yi, ọpọlọpọ awọn ọlọtẹ ni nwọn lẹ ṣogbọn lati ko ẹrọ bọ ọ lọwọ lati fa sinu ọtẹ ti nwọn ndi, ṣugbọn nipa iwa rere ati inu funfun rẹ, ko gba wọn laye arara, o dojuti wọn to bẹ ti nwọn ko fi le de sakani ọdọ rẹ mọ di ọjọ opin rẹ yi.

Nigbati o gbọ wipe awọn Ilu nfẹ dibo fun Lọya Adebayọ Doherty lati ran lọ si Igbimọ-Aṣelu (*Lagos Town Council*) ninu oṣu June 11, ọdun 1926, inu rẹ dun pupọ lati gbọ, o si yọnda ọmọ rẹ yi lati jẹ ki o lọ sinu ipo na, a dupẹ lati ri wipe a ko le ṣiro iye iṣẹ ribiribi ti Lọya Adebayọ Doherty ti ṣe fun rere ilu ni Igbimọ-Aṣelu na ati eyi ti o si nṣe lọwọlọwọ ohun anfani kan ko ju eyi lọ, nitori bi Doherty ke yọnda ọmọ rẹ fun ilu lati jẹ ki o lọ si ipo yi, kini ilu ti ṣe le ri iru anfani ti ọmọ rẹ yi nṣe fun rere ilu yi loni ! !

Bi Doherty ba si jẹ ẹniti ko fẹ rere ilu rẹ, dajudaju inu rẹ ko le dun si aba ti awọn ilu da nipa rẹ.

A fẹ ki ẹ fa awọn ẹniti baba nyin fi ṣe Baba-nsinku rẹ mọra, ki ẹ jumọ ma jẹ ki gbogbo ohun ti o ba nlọ ye ara nyin daradara, nipa eyi, ki yio si kila-kilo ọkan lẹhin oku baba nyin, gbogbo nkan yio si ma lọ daradara lai tẹ lai wọ, gbogbo nkan mbẹ lọwọ Sati, ki ẹ si ma fi adura ti i, ki o le gbọ ohun nyin, ki o si le jẹ ki ẹhin baba nyin fẹrẹ dara ju oju on tikalarẹ lọ—ki Ọlọrun na si ma ṣọ gbogbo nyin o.

BABA-NSINKU.

Ọgbẹni Martins, Carrena ati Ṣogbẹsan—awọn mẹtẹta yi ati awọn ọmọ rẹ pẹlu li a gbọ wipe Doherty fi ṣe Baba-nsinku, kini a npe ni Baba-nsinku ? Ẹniti o ntun ẹhin oku ṣe lo njẹ bọ, ki iṣe baba ti a haya pe ki o gbe oku ru lọ si itẹ lọ sin.

Lode ti a wa loni, ọpọlọpọ Baba-nsinku lo ti jalara; ẹniti ko le tun ẹhin ọmọ ẹnikeji rẹ ṣe, ọna wo ni ẹhin irufẹ awọn ẹni bẹ ti ṣe le dara, a ko tilẹ tanmọ pe atubọtan iru awọn ẹni baun le suwọn, ọran ẹ̀pẹ́ kọ o—Ọmọ iya, otitọ ọrọ gan li a nsọ fun 'rawa.

Ẹniti o ba si nfẹ ki ẹhin ti on dara, o ni lati tun ẹhin ọmọ-ẹnikeji rẹ ṣe, a ko ni ọrọ pupọ lati sọ nipa eyi ki Ọlọrun fun nyin ṣe o.

OLOGBE ALAJI FAHM OLORE.

Ọkan ninu Imale ilẹ yi hanunhanun ni Alaji yi nṣe, ṣáṣá enia ni ko ṣai mọ o ni igba aiye rẹ, bẹni ṣaṣa ni ẹniti Alaji na ko ṣe ōre fun, gẹgẹ bi nwọn ti nsọrọ iku Doherty bẹni nwọn nsọrọ iku rẹ nigbati on na ṣe alaisi.

Lati igbati o ti jalaisi, a koi ti ri Imale miran ti o le dide lati ma tẹ le irufẹ ilana wọn ni samọni aiye tiwọn.

Bẹ a ko le fẹ iru ẹniti o le ṣe bi wọn ku ninu Kiriyo ati Imale di bi a ti nwi yi, ṣugbọn nwọn ha le ṣe bẹ bi ?—Iwa ọtẹ iwa jamba, iwa buburu gbogbo bawọni ko jẹ ki nwọn le ranti iwa rere ti awọn ẹni wọnyi nhu ni igba aiye wọn, ki nwọn si ma kọ iṣe wọn.

Ṣugbọn ti o ba jẹ wipe ọtẹ kan ni nwọn fẹ di si ẹnikan ni, o daju pe yio ya wọn lara, tobẹ ti ẹlomiran ki yio bikita lati ṣe inawo ki inawo eyi o wu ti nwọn le sọ wipe ki nwọn ṣe larin arawọn ; rere wo lo ha le ti di rẹ jade fun wọn lọjọ ikẹhin, awa ko ro bẹ arara.

Alaji Fahm ti a ti fi ọrọ Doherty wé loni, ẹniti o ba wa ni ilu yi lọjọ ti nwọn fi ngbe wọn re itẹ, yio mọ dajudaju lọjo yi, pe ẹni aiye ba yẹ lọrun yio yẹ.

A si ro wipe irufẹ awọn ẹni bayi nwọn ki iṣe ẹniti ilu le tete gbagbe bọrọ, ko kan ti wipe nwọn fi ọmọ saiye lọ ti yio ma jẹ ki enia le ma ranti wọn—ṣugbọn bi olukuluku awọn ẹniti irufẹ awọn ẹni wọnyi ti ṣe lore ni igba aiye wọn ba tilẹ nranti ohun ribiribi ti nwọn ti ṣe fun wọn nipa eyi ki yio le jẹ ki orukọ wọn le parun giri.

Ko si igba ti ilu kọ le ma ṣai ṣe iranti irufẹ awọn ẹni wọnyi, orukọ won yio ma bẹ ní ẹnu enia titi gberé ! o nwu ọpọlọpọ enia, o nwu olowo o nwu talaka, o nwu ọkunrin o si nwu obinrin pẹlu ki ọjọ iku on le dara bi o ti tọ ki o yẹ Ọmọluwabi, ṣugbọn ọna ika, ọna jamba, ọna fọlufọlu ọna hiha owo mọ'wọ fun awọn alaini ani ọna tẹmbẹjẹkud kọ ni ọjọ ikẹhin enia fi le dara ti aiye le yẹ ki ọrun to yẹ, bikoṣe ni ọna lila ọwọ fun Akusẹ ati Alagbe ti ebi npa ni ọna iforibalẹ fun ẹniti o julọ, ni ọna ọyaya ati ni ọna ipa ofin Ọlọrun mọ ni ọjọ-iku ọmọ Anabi Adamọ fi le dara.

Ọpọlọpọ awọn ẹniti o to rekọja lọ si *Qiyaomat* lo mọ irufẹ ohun ti oju on ti ri tan ni *Sare*, iba je wipe ẹniti o ba ti ku tun ntun aiye wa lẹnkeji, nwọn ba rohin titi ẹnu iba fẹrẹ bo, o dun wa pupọ

pe enia ki iku lẹnmeji o mbẹ ninu ọgọrọ enia ti o jẹ wipe ti nwọn ba npọka-iku lọwọ aṣọ ni nwọn fi nha wọn lẹnu, ki onile keji ma ba gbọ ifun ọni ti nwọn ntu, irufẹ awọn ẹni bẹ ha lero pe ọrun le dara fun wọn agbẹdọ arara ! ? ?

Ki olukuluku lọ ko iṣe awọn ẹni atata ti a nsọrọ wọn yi, ki aiye ati ọrun le dara fun wọn—ẹni a ba wi fun ki o gbọ, ẹniti ko si gbọ kẹ, o ku oluwarẹ pẹlu iwa rẹ, Ọba Adakẹ dajọ mbẹ ; A tọrọ adura fun awọn ẹni rere, ki Ọlọrun fori jin wọn ki o gbe wọn si afẹfẹ rere, ki o si jẹ ki ẹhin wọn dara fun wọn ju lọ.

## IWE IPIN OGUN ATI BABA-NSINKU !

Gbogbo nkan lo ni samọni tirẹ, gẹgẹ bi awọn ẹda ti ni samọni, bẹni samọni mbẹ lori ohun gbogbo ti a nmu ṣe.

Ni sa lailai, bi enia pataki tabi olowo kan ba fẹ ku, bi o ba si jẹ ẹniti o ni ohun dukiya lọwọ daradara ẹwẹ ti Ọlọrun ko si fi ọmọ jẹ niya, yio ṣe iwe silẹ pe barato bi ọlọjọ ba de lati fi ṣe eto bi ohun-ini yio ti lọ si ki o ma ba jẹ ohun ti yio mu akatakiti dani larin awọn ọmọ on.

Gẹgẹ bi o ti jẹ wipe alamọri Ogun—*estate* lagbara pupọ larin awọn ọmọ ; bi enia kan ba pin ogun silẹ ti o si yan baba-nsinku ti i lati pin ogun fun awọn ọmọ-orukan, bi ogun ti baba na ba pin silẹ ba yapa tabi ti o ba fẹ mu irẹjẹ dani larin awọn ọmọ, omiran le dide ninu awọn ọmọ lati ri wipe on sọ irufẹ ogun bẹ di oku lori eyi ijangbọn ati ede-aiyede yio de si arin awọn ọmọ tobẹ ti aye yio fi wa fun baba-nsinku lati fi ogun bẹ ṣe yẹyẹ irufẹ yẹyẹ ti a le sọ wipe ko ni jẹ ki awọn-orukan na ri itẹlorun ati igbadun ninu ohun-ini ti baba wọn fi silẹ.

Ṣugbọn baba-nsinku ti o ba gbọn ti o si mọ ohun ti on nṣe ti o si ri gbangba wipe ti on papa ba papoda ni ọjọ kan elomiran ni yio ṣe oju on tikalara on ẹwẹ ti ki isi iṣe ọdalẹ enia, ti o ba ri wipe ogun bẹ le mu ijangbọn dani larin awọn ọmọ ẹtọ rẹ ni wipe ki o ba ẹni bẹ ṣe sawura daradara gẹgẹ bi ara rẹ, eyiyi ni ẹtọ pataki lati ṣe. Bi a tilẹ ri ẹniti o lọgbọn dara-dara ti o si mura lati ṣe iwe-ipingun gẹgẹ bi o ti tọ ti ko le mu iregbe ati akatakiti fun awọn ọmọ rẹ, ero ibajẹ ti o mbẹ ni ọkan won lati ṣe sori ogun na nigbati ọwọ wọn ba tẹ iku-ida tan, ki yio le mu wọn sọ wipe ẹtọ ti ẹniti o ni ogun na ṣe iwe rẹ dara pupọ, tobẹ ti nwọn o fi gba oluwarẹ ni imọran lati yi ogun na pada si ọna aito ; irufẹ Baba-nsinku baun ọdalẹ, ati oni-makaruru enia lo nṣe.

Ki a ṣe iranti aseko kan ti o jẹ wipe ọpọlọpọ olowo ni Kiriyo ati Imale nku ni ilẹ yi ti nwọn si nṣe iwe-ogun silẹ fun awọn ọmọ ẹbi tabi aya wọn a ko tanmọ pe wahala ọran ogun le to bayi, ki a si wa wo aseko ti a tun wa loni bi ọran ogun ti le bi ẹnipe nwọn ṣẹṣẹ bẹrẹsi da ogun pipin silẹ ni ilẹ yi ni, kini ha fa sababi rẹ iwa ọdalẹ ati iwa makaruru lo mba Baba-nsink miran ja.

[*Koi li pari.*]

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

## SUNDAY SCHOOL EREKO DI ANỌGA WO.

[ Lati ọwọ Ọmọ Awo ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Awọn Ile Iwe ọjọ Isimi ti Church Ereko nṣe ohun ara, ape ni, si ibi ifi patako ẹbun eyi ti awọn oyinbo npe ni Shieeds fun Class meji to dawọju fun Quarter, ati ti o si tun nwa dede si Sunday School. Iru ohun ba wọnyi wu ni lori pupọ nigbati a gbọ iye ti nwọn da tun odindi ọdun kan ati iye ti wọn tun da fun oṣu mẹta pere ; ati aropọ bi wọn ti nwa si fun oṣu mẹta pẹlu ti eṣi, adupẹ pupọ fun iru awọn ẹniti Sunday School Committee ti wọn da iru nkan bayi silẹ lai fi ọta pe iṣẹ Oluwa ni lati lọ, o si tun jẹ ohun iwuni lori lati ri bi awọn agbalagba papa lobinrin ti nwa si Sunday School, adura wa si ni pe, ki Oluwa toju ile ati ọna awọn ẹniti ko fẹ ki iṣẹ Oluwa bajẹ. Alufa Ijọ na lo ṣe alaga fun wọn Rev. M. O. Ddada, Bros. E. B. Dada ati O. S. Dawodu si gbe lọtun ati losi, njẹ Superintendents ati Secretaries Sunday School. mo gba fun nyin o. Ẹjọwọ o iran nyin dun wo, igbakugba ti ẹ ba fẹ ṣere, ẹjọwọ ẹma pemi o, ka ba ma fi onjẹ oju fun oju, ọwọ nyin a ma roke gbogbo o.—Amin.

## ẸGBANI O, ITUMỌ CAKE TI NWỌN NGE NI ỌJỌ IGBEYAWO.

Awọn agbagba ma npa lowe pe berẹ-bere kinṣi bere, ati pe ohun ti ko ba ye ni, ti a ba bere ki nṣe ẹṣẹ, ninu gbogbo ohun ti ẹ fi nṣe ti Igbeyawo gba, gẹgẹ bi ọyin, orogbo, obi ati gbogbo nkan miran to yẹni perepere, ṣugbọn a ko mọ itumọ ti Cake yi, inu wa yio si dun bi a ba rẹni ti o ba le ladi rẹ fun mi, ti o ba jẹ pe aṣa oyinbo ni, kini ha ṣe ti oyinbo ki nlo Cake nibi Iyawo wọn, nitoripe ọpọlọpọ lawọn oyinbo ti o ngbe Iyawo leko, a ko si gbọ pe awọn Baba nla wa nge Cake nigba ti wọn, wọn pa nitan fun ni pe oyin, orogbo, ati obi, wọnyi lawa nlo nigba lailai, ewo ni ti Cake o ẹ gba wo. Bi o ba si jẹ pe, ki a leri

ohun fi fun awọn enia ni, ọpọlọpọ Iyawo lagbe leko ti wọn ko gẹ Cake nibẹ, bẹni Iyawo na ko ṣe ro, ẹgan ni hẹ, ko dede ti afi nsọ iru ọrọ bayi sinu Eko Akete, a ri lagbaja kan ti o jẹ pe nigbati ti o ma gbe Iyawo niṣe ni o lọ ya owo fun oni Cake nigbati ọgbẹni ko le san owo yi mọ ngbọ kabọ ẹlẹmi kan tabi meji ha nṣe ohun kekere bi, odi ki wọn ma tun ara wọn sira pe alakọri rẹ, nigbati o nsun kun owo Cake wa ba mi niṣe bi emi ni mo gba ọ la, ọrọ re o ẹyin ọkawe Eko Akete, bi oṣe pe, ko lọ yawo Cake nisisiyi aṣiri rẹ yi ko ni tu, Oluwa ma tu aṣiri wa o, njẹ mo bere ti o ba jẹ pe, Cake yi ki nṣe ọran yan kini ha mu lagbaja lati lo yawo nitori Cake, ki nto le sọ ọrọ kan pataki si idi Cake yi, o di igba ti mo ba ri ẹniti o ma ladi tabi lati sọ itumọ rẹ fun m, o si daju pe, ki nṣe gbogbo awọn ti o ti gbe Iyawo Arede, tabi ti o fẹ gbe Iyawo Arede lo mọ itumọ ohun ti Cake jẹ ni Igbeyawo. Mo ranti pe ọdọmọkunrin kan, kọ iwe kan (an open Letter) si ẹni ọwọ kan (a minister) pe ko jẹwọ so idi tabi itumọ, odi janrẹrẹ bi mejila ti wọn fi ndana obinrin. O tun bere pe, ọranyan ni pe, bi enia ko ba ni agbara ati ra awọn ọti yi ṣe kole gba Iyawo niyen tabi ọranyan ni pe ki amu oti bi mejila tabi jubẹ lọ fi dana Iyawo. Ko da mi loju pe ẹni owọ yi fi esi si ọrọ na titi fi di oni oloni, bẹni bere bere ki nṣi bere. Toto owe ni o.

Emi mura tan pẹlu osunsun mi kuduru pẹlu ọpẹ inu iwe fun ẹni ti o ba le sọ itumọ Cake ti wọn nge lojọ Iyawo, kole dami loju pe, aṣa ni debi pe ki enia lo ya owo nitori ati ge Cake lọjọ Iyawo. Mo tun wipe, bi o ba jẹ pe, nitori ati ri ohun fi fun enia ni a le ri Cake na ti o ma pọ, (quantity) ti osi ma din ku (cheap) ju eyi ti wọn ṣe nitori ti Iyawo lọ asi fi ọrọ na silẹ na titi awa fi ri ẹni ti o ma sọ fun wa, mo nreti o?

## IYAWO DUN LỌ ṢINGIN ỌKỌ TUN MI GBE

O ta si wa leti fiorin pe Ọgbẹni D. B. Davies, ti Treasury fẹ gbe ọmọge kan ni Iyawo, Miss. Sarah Laitan Davies ni ijọ Alamisi ti mbọ ni agogo mẹwa-abo ni Ṣọọṣi Tinubu, 26th April 1928, at 10.30 a.m., Tinubu Church, Lagos. Antara yin o. Davies to Davies, Oluwa ko mọjọ ro o. Ewolewo Bababunmi, ko lọ san ṣokoto rẹ dara-dara, ko si mura omi Igo oloje to pe, ki iṣ omi Iju o nitori gbogbo wa lansan owo omi Iju.

Emi ni tiyin nitotọ,
ỌMỌ AWO.

---

**To Lease.**

A House at No. 152 Upper Street, Lagos.

Iso ti o wa ni Ck:-Arin jẹ *pound* kankan ni ọdọdun kiṣe oṣoṣu.

## IYA OLOGBE J. H. DOHERTY.

Si Oniwe-irohin Eko Akete,
Eko.

A tọrọ aye diẹ ninu iwe irohin nyin aladun ti ọsẹ yi lati fi awọn aṣiṣe diẹ han oniwe irohin Akede Eko ninu iṣẹ nlanla to tiṣe nipa kikọ Iwe Akanṣe Itan Igbesi aiye Ologbe J. H. Doherty.

Awọn aṣiṣe na ni nipa ibilẹ, ibi iku ati sisin, ati iṣẹ iya Ologbe J. H. Doherty ti o kọ sinu iwe rẹ ti ọsẹ to kọja.

Iya Ologbe J. H. Doherty ki ṣe ọmọ ibilẹ Addo Owi li Ekiti. Ọmọ Ọba ilu Ijero ni iṣẹ. Ọba na la npe ni Odundun a sode dẹrọ. Abiso iya yi, ni Fatoregun Ariwodọla.

Ni ilu Ijero ni iya Ologbe J. H. Doherty ku si, gẹgẹ bi o ti fẹ ki on ku silu on, nibẹ ni a si sin pẹlu ẹyẹ nla nla, nibẹ ni Ologbe J. H. Doherty si ti lọ nigba aiye rẹ pẹlu awọn korikosun ọrẹ rẹ bi awọn ọgbẹni Ijalẹ, Carrena, Ogunlaiye, Bishop Howells ati awọn ogu logọ ọkunrin ati obinrin ti o ba lo, ki a ma tilẹ tun sọ ti awọn ọmọ ologbe J. H. Doherty papa to lọ ṣoku iya Baba wọn ni Ijero.

Nitotọ ni iya ologbe J. H. Doherty jẹ olufọkansin papa ati onihinrere, kiṣe wọnyi nikan, o jẹ olufẹ ilu rẹ, o jẹ obinrin bi Joan of Arc ati Mary Davies. ṣugbọn ko da ile Ọlọrun kọ si ilu Ijero, ṣugbọn owo on ara ti o na si ile isin tuntun ti nwọn ti kọ si Ijero o to Ọlọ́a didu loye, toto o!

Ipese owo ti o wa fun ilu Ijero kiṣe fun ile Isin Ọlọrun bikoṣe fun ile ẹkọ. Ipesi yi kiṣe inu iwe ogun li o wa. Ologbe J. H. Doherty papa lo fun Church Missionary Society ni £2,000 egba poun fun iranti iya rẹ ati ele ti owo yi ba nle Ịdọdun ki a ma lo fun ilọsiwaju ile iwe ti o wa nilu Ijero. o si ti bẹrẹ, si owo yi lilo loju aye rẹ. Ore ti Ologbe J. H, Doherty ṣe ki o to ku ju ilọpo mẹwa eyi ti o wa ninu iwe ogun.

"Iya Ọga doṣupa" ni orukọ aṣọ ti a fi ṣe aṣọ ẹbi oku iya ologbe J. H. Doherty yi nitori bi oṣupa ni iya yi nran nigba aiye rẹ, nitorina a nireti pe yio ma ran bi oṣupa bakanna lọdọ Olodumare.

A kọwe yi, kiṣe nitori owu jija fun ilu wa ṣugbọn nitori ọrọ ki ipẹ di itan, ohun ti a ba si ṣe loni ni itan ọla, ki awọn iran to nbọ ma ba gbe ọmọ ọ'ọba fun Ọṣun. Ohun ti a ba kọ sinu iwe itan igbesi aiye enia o jẹ ẹri pataki lẹhin ọla nitorina la ṣe ja nyin ni koro o, Oniwe Irohin Akede Eko.

Emi ni tirẹ nitoto,
R. F. ỌMỌTADE,
170, Bamgboṣe Street,
Lagos.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, APRIL 21, 1928.

## O SUNAN SUNAN Ș'ỌMỌ DOSUNMU, GBẸRE RẸ Ẹ Ẹ.

Oriki tabi pipe ti a pe Prince Eșugbayi Eleko lọsẹ yi ḷeyi; ki șe pe on nikan pere ni Ọba Dosunmu bi, ndao, Ọba Dosunmu bi ọkọnrin, o si bi obinrin ki o to w'aja; ọrọ ẹjọ Prince Eșugbayi Eleko ti o ku si dẹdẹ lakoko yi lo mu ni pë ni o sunan sunan ș'ọmọ Dosunmu; gọgẹbi a ti nsọ, riro ẹjọ rẹ ni'ila Oyinbo ti di mimọ fun t'ọkọnrin, t'obinrin, t'ọmọde, t'agba jakejado igboro Nigeria; ki ișe pe a ko ri ọrọ miran sọ mọ, lo tun mu ni na'wọ gan ọrọ yi loni, șe ẹuyin ọkawe wa na mọ pe ko ni tan ninu igba osun, ki a ma ri fi pa ọmọ lara; pataki ohun ti o mu ni sọrọ ẹjọ na ni pe olukuluku enia lo nnọga pe gẹgẹbi nwọn ti mọ pe ninu igba yi ni awọn Atabatibi Ol fin ilu Ọba n viyẹ ẹjọ na wo si, o yẹ ki a șe awọn enia ni iranti pe boya laipẹ ogongo ḷẹrẹ sọraki na: șe suru ti o mi ẹ ninu riro ẹjọ lọna ti Gẹsi ko șe rẹ; o yẹ ki eyi ki o ri bẹ; nitori ki awọn agbalagba ti nwọn t'oro lọ le mọ apade alude bi nkan ti lọ si: ișe ọwọ ro ẹjọ ti awọn Gẹsi ko dabi "Kodurogbẹjọ" ti awọn ilu miran, idi rẹ niyẹn ti o nri loju ẹlomiran bi ẹnipe ijafara wa ni ẹjọ riro lọna awọn Ọmọ Auansara; lọna keji ẹwẹ, eto ọpọlọpọ lo mbẹ ninu riro ẹjọ lọna ti Gẹsi, ẹjọ ti Prince Eșugbayi Eleko ko șa mu eto ọpọlọpọ dani, orișirisi iwe ti o yẹ ti o si tọ ni t'ọtun t'esi awọn Lọya ti yio gba ẹjọ riro, ni lati șe ipalẹmọ rẹ silẹ gẹgẹbi a ti sọ ri, ko si ẹniti ẹjọ Ẹniaiye-nfẹ yi mu lọkan to awọn ọgọrọ ninu awọn enia wa ti nwọn mọ riri ohun ti o șelẹ ni ọdun kẹta ẹhun; a gbọ pe lati *Tuesday* ọsẹ yi ni pupọ ti ndagiri bi awọn yio ri irohin aladun kan gbọ lati ilu Ọba wa: o yẹ ki eyi ki o ri bẹ, oju ko ni se igi orere, afomọ ajagẹmọ ko ma s'abuta; șașa enia ni ọrọ Eleko ko dun, ki ișe nitori nkan meji bikoșe nitori ifẹ nlanla ti nwọn ni si

Nitotọ ọdaju ọmọ to nge ika (*finger*) lo pọ, șugbọn sibẹsibẹ a ko ni șai ri awọn "ẹru Ọlọrun o r'ẹru fori ti igi" miran ti nwọn ngba ọran ẹni dun. Bi a ti nwi yi boya iporogan bibẹrẹ si ẹjọ na le șẹlẹ laipẹ, ko si si ișẹ to ku ni mimușe bikoșe titẹwọ adura si Ọba Săti; a dupẹ pe Ijọba ko fi lilọ ke si Ọmọ Alade na ni igboro Ọyọ du ẹnikẹni, șugbọn bi o ti wu ki eyi dara to, ki o le tun padi wa si arin wa ni ifẹ aimọye enia nihin ati ni ibomiran; loju awọn miran o dabi ẹnipe ilu ko kọ ibi ara si labari na mș, șugbọn ẹ jẹ ki irohin ojiji de na, ti o mu oyin-aladun dani, nigbana ni ẹ o ri irọkẹkẹ ati ẹsẹ girigiri ni igboro, gbogbo nyin lo mọ ayọ nla to mbọ nijelo nigbati a gbọ pe awọn Adajọ yọda riro ẹjọ na lọdọ wọn lọhun; a mọ pe ninu palaba ninu șigidi ẹrẹkẹ a șe kan, eyini ni pe a ko ni șai gburo bi nkan ti nlọ si ni Kotu Apili ọhun bi o ti wu ki o ri, awọn ẹlomiran le ma yọ ṣẹṣẹ si ipo ti Ẹni-ilu-nfẹ na wa loni, eyi ko ya ni lẹnu, bi aiye ti ri niyẹn, Aiye Akamara, eyi si mu ni ranti orin kan ti o lọ bayi pe:—

Ko ma s'ẹni ti ko ma kan
Ile ẹjọ nla,
Oniye
Ile ẹjọ nla,
Awọn to ti nyọ ṣẹṣẹ
Awọn to ti nyọ ṣẹṣẹ
O mbọ wa kan wọn o,
Ko ma s'ẹni ti ko ma kan
Ile ẹjọ nla.

Ki Baba ṣọ ni nibẹ.—Amin, Așẹ.

---

## ATARÈDÈ ATARÉDÉ KA GBỌ TI JESU RE MO MỌ.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU. ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Li oju ọpọlọpọ Ṣọși awọn Kiriyo Eko ati ti ilu miran, ọkunrin tabi obinrin ti o ba gbe arede tabi iyawo, o pegede; ọjọkijọ ti oluwarẹ na ba si ku, ti o ba kan ilẹkun orun rere ko, ko, ko, bi St. Peter, ẹniti a gbọ wipe o wa li oju ọna ba bere wipe, Iwọ tani yẹn? Ti o ba dahun wipe, oo

Lagbaja ni, bi o ba si tun bi i lere wipe, iru enia wo ni iwọ jẹ li aiye? Ti oluwarẹ ba dahun wipe, igba kan ṣoṣo pere ni on jale, ti Ijọba si fi on si ẹwọn ọdun meje, lẹhinna, on ta tẹtẹ on nmu ọti, ti on ba si purọ mọ ẹnikan, Ọlọrun nikan ni o le yọ oluwarẹ kuro ninu wahala na, on si fẹran ọkunrin pupọ. Ti St. Peter ba si tun bere lọwọ rẹ wipe, Iwọ ha gbe arede bi? Ti obinrin na ba ṣa ti le f'esi bayi wipe, on gbe arede, Mrs. Lagbaja ni on, on si gba oruka; werewere ni a o ṣi ilẹkun fun u, ti yio wọ ile, ti yio si joko ti awọn aṣiwaju rẹ nibẹ, ti nwọn o si ma jumọ kọ orin:—

"Ire t'a su ni Eden,
Ni'gbeyawo kini;
Ibukun t'a bukun wọn,
O wa sibẹsibẹ"

Ṣugbọn, ẹniti o ba sọ fun St. Peter wipe, on ko wọ ẹwọn ri, on ko mọ ọti mu, on ko purọ mọ enikeji on ri, on ko nta tẹtẹ, on nṣe itọrẹ anu fun talaka gẹgẹ bi agbara on ti mọ, on bẹru Ọlọrun, on ko si pe orukọ Rẹ lasan ri, on npa ofin mẹwa mọ. St. Peter yio gb'oju mọ ọ wipe, Itan ni gbogbo 'yẹn; o gbe arede tabi o ko gbe? Ti o ba gba Oruka, ki o wọ ile, bi bẹ ko, lọ si ọdọ *Lucifer* li Ọrun Apadi, ibẹ ni ile awọn Madam ati Daddy ti ko gbe iyawo.

A ha fi Kristi kọ nyin bẹ, ẹnyin onikekere Igbagbọ? Onigbagbọ-ki-onigbagbọ ti o nro iru ero bayi, ntan ara rẹ jẹ ni; a ko ngbe iyawo li ọrun, bẹni a ko si nfi nwọn fun-ni ni iyawo ni ẹ. Igbeyawo, ohun aiye ni: olukuluku orilẹ-ede li o si ni aṣa tirẹ!

Aye ko si fun wa li ọsẹ yi lati to eto oniruru igbeyawo orilẹ-ede gbogbo li ẹsẹsẹ, (iyen ti a ba tilẹ le ṣe bẹ,) ṣugbọn a le sọ niba ṣoki wipe, iru igbeyawo ti ọpọlọpọ Ṣọṣi gba kan'ri nisisiyi bi ẹṣiṇṣin gba igba ọti jẹ awokọ, tabi itunje lori isin igbeyawo awọn aborisa ilu Romu—ilu ti o la awọn Oyinbo Gẹsi l'oju, ti o si ran Bishop Enia Dudu kan, Augustine, ẹbi Oduduа, ẹniti o pada di Archbishop lẹhinna lọ ni A.D. 597. (ẹdẹgbeje ọdun, o le mẹtadi-logbọn nisisiyi) lati lọ wasu Ihin-rere fun awọn Oyinbo, lẹhinna ni nwọn bẹrẹ si di Onigbagbọ ni eni-tere, eji-tere, ki awọn papa to di ẹniti o nni Deacon, Archdeacon, Bishop, Archbishop li arin wọn loni, ti nwọn ko si fẹ lati fi Enia Dudu jẹ oye Bishop kikun mọ, bikoṣe oye pẹ-pẹ-pẹ miran.

Nigbati awọn Oyinbo kọkọ gba ọjẹgẹ igbeyawo olobinrin kan, yala o rọ wọn lọrun, tabi o ni wọn l'ara ni o, awa ko mọ. Ṣugbọn gẹgẹ bi iṣẹ, oṣi ati airikanṣekan ti pọ to ni ilu wọn, ati bi iya ile ti jẹ wọn to, ti o ṣe wipe ipa ati inira nla ni ẹnikọkan ninu ọkẹ aimoye enia fi le ri owo haya oju'le kanṣoṣo fun ara rẹ lati gbe, a ko le ṣe aiki ẹniti o ba jaja ṭitakaṭtiraka gbe obinrin kan ni iyawo wipe, o ku inawo!

Aṣọ-ẹbi, kil'o njẹ bẹ? Owo ti awa Enia Dudu fi ngbe iyawo kan, Oyinbo le fi gbe mẹfa. Sibẹsibe, a ko mọ ohun ti a nṣe. Iya ti ọkọ alarede miran fi njẹ aya rẹ ko kere; ọpọlọpọ alarede ha kọ ni obinrin ita ko jẹ ki o kia (*care*) fun ti ile mọ, li aika ognnlogọ awọn obinrin ti ale (*Sweetheart*) ọkọ wọn npa owe mọ li ọja Ereko ati Ita Faji?

Ki nto ma jẹ faji ọrọ nṣo, mo fẹ ki o ye gbogbo enia gbangba wipe, nko kẹgan arede, nko wipe o dara lati ni obinrin pupọ ju ẹyọ kanṣoṣo lọ, ohun ti mo ngbidanwo lati sọ ni wipe, sẹria ti o sọ Oyinbo di olobinrin kan ninu ibọrisa wọn, ki ẹsin Igbagbọ to de arin wọn, ati wipe, nitorina, a nṣe ete l'ọṣọ ni nigbakugba ti a ba npe e ni ti Onigbagbọ tabi *Christian Marriage*.

Nko jiyan wipe a ko le tumọ igbeyawo "*For better for worse*" ko ba diẹ mu ninu ọaọ Testament titun, ṣugbọn mo sọ ọ, mo tun sọ ọ wipe, Oyinbo ti nṣe "*For better for worse*" li arin ara wọn ki nwọn to mọ rara wipe Iwe kan tilẹ wa li aiye ti o njẹ *Testament* lailai, tabi *Testament* titun.

Nipa ọrọ obinrin, awọn ti a le pe ni janduku ti ko ni ẹbun imaraduro li o kun inu *Testament* lailai tẹtẹ, awọn ẹni bi Dafidi ati Solomon ọmọ rẹ ti o ni ẹdẹgbẹrin aya ati ọdunrun ale, (*Seven hundred wives and three hundred concubines!*) ṣugbọn ni ikẹhin, o ka gbogbo wọn si asan ati imulẹmofo. Abrahamu papa ti a sọ fun wa wipe on ni apẹrẹ igbagbọ ati ọrẹ Ọlọrun, ko duro ti Sarah nikan!

Ko di ni loju wipe *Testament* titun yoda ikobinrinjọ, ani, St Paul tilẹ fẹran *Bachelor* tabi Apọnṭotọ-tot, ti ko ni obinrin rara jẹ eni ti o ni aya kanṣoṣo lọ, l'a bikita, boya, fun aṣẹ Ọlorun ti o sọ wipe, "Ki a ma bi si i, ki a si ma rẹ si i."

Ipinnu olobinrin kan yi ba aṣa Oyinbo, papa ti Gẹsi mu; aṣa wọn, ani, li akoko ti nwọn tilẹ nbọ igi, bọ ọpẹ. Nitorina, nigbati nwọn di Onigbagbo tan, nwọn fun ika mọ ọ girigiri, nwọn si fi ofin gbe e l'ẹsẹ.

Dajudaju, ati l'aisi ani-ani, ibaṣe wipe ikobinrinjọ ni aṣa ilu wọn tẹlẹ ni, ki Enia dudu jẹ olobinrin kan, Ọba ilu Oyinbo miran iba ṣe ju Solomon lọ. Gẹgẹ bi apẹrẹ, nigbati Jesu kọ wa ninu Testament titun wipe, "Bi ẹnikan ba gba ọ li eti ọtun, ki o yi ti osi si i," ti ofin Oyinbo si wipe, "Bi ẹnikan gba ọ li eti otun, ki o pe e l'ẹjọ si Kotu:" ewo ni Oyinbo tẹle ninu mejeji, ofin tiwọn ni, tabi ti Jesu?

Awọn Loya tabi Amofin ti Jesu fi bu ninu *Testament* titun ha kọ ni awọn enia pataki julọ ni Ilu Oyinbo l'oni?

Nigbati Iwe-adura ti Ṣọṣi kilọ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ gbe aburo tabi ẹgbọn aya rẹ ti o ku ni iyawo, Oyinbo ko ha ṣe ofin wipe, enia le gbe e ni a-gbe-dara. Nigbati Jesu ni ki a ma ṣe itọrẹ-

anu fun lalaka ati alaini, Alumọngeri tabi Onibara kan ha gbọdọ tọrọ jẹ ni Ilu Oyinbo, ki o ma di ẹti si i l'ọrun?

Pupọ bẹ ni a le ka ti o jẹ wipe ibikibi ti ofin tabi aṣa Oyinbo ba yatọ si ofin Bibeli, ofin Oyinbo ni nwọn njẹ ki o b'ori; nitorina, nigbakigba ti a ba ri ofin tabi aṣa Ilu Oyinbo ti o ba ti *Testament* lailai tabi titun mu, o ṣeṣi bọ si i ni, ki a ma si ṣe ro wipe, ofin Onigbagbọ ni.

Ofin arede obinrin kan yatọ patapata si *Testament* lailai, ti o ba si ba *Testament* titun mu, o ṣeṣi ni, iyẹn ko pe e ni igbeyawo Onigbagbọ rara, aṣa Ilu Oyinbo lasan ni.

Ohun ti o dara pupọ fun okunrin ni lati fẹ obinrin kanṣoṣo, ki o si ya ọna agbere silẹ. Itẹlọrun ti alarede iyawo ẹlomiran nfun u ni ile pọ tobẹ gẹ, ti ọkọ rẹ ko tilẹ jẹ fẹ ehin si obinrin miran li ode, de ipo ti o ma ṣ'ẹju si i. Ṣugbọn eṣu beleke ni aya, eṣu beleke ni ọkọ alarede miran.

Ni Ilu Oyinbo papa nko, omi igbin ko tu igbin, ẹni he ni on he ẹrọ. Ojojumọ, ọsọsẹ ha kọ ni t'ọkọ-t'aya ngbe ara wọn ni iyawo l'oni, ti nwọn si ngba Iwe-ikọsilẹ ni Kotu l'ọla; igbagbogbo ha kọ ni awọn Mrs. Oloruka nkọ iwe nibẹ si ọkọ wọn wipe ki o jọwọ pe wọn li ẹjọ ikọsilẹ, nitori awọn ti da ilẹ li aṣiri pẹlu okunrin miran, ẹniti awọn fẹran pupọ ju ọkọ wọn lọ, ati wipe, awọn si ti wọ ẹwu Buba B'o-n-fo, lati ba ale (*Sweet-heart*) wọn na lọ si ibikibi l'abẹ Ọrun?

(*Koi pari*).

Emi ni ti nyin nitoto,

ATARI AJANAKU.

---

ORI III.

## IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KARUN.

---

Ti a ba wa ni ọdọ awọn ẹlomiran, a dabi ẹnipe afẹfẹ iwa ti Ọlọrun nbu lu ni, a tu ni lara, a fun ni ni okun, bi ẹnipe a wa ni ori oke giga ti afẹfẹ rẹ nlu ni, tabi bi ẹnipe a nya orun pẹlu igbadun.

Agbara iwa tutu ti Sir Thomas More ni, pọ tobẹ ti, bi iti mu awọn enia buburu gba tirẹ, bẹ na ni imu awọn enia rere tubọ hu iwa rere. Lord Brooke sọ nipa Ologbe ọrẹ rẹ, Sir Phillip Sidney, pe, "ọgbọn ati oye rẹ mu ni ifẹ ki on ati awọn ẹlomiran le jẹ ẹni rere, ki iṣe nipa afi-ẹnu-sọ ni, ṣugbọn nipa iwa ati iṣe."

Fifi oju ri enia nla ati ẹni rere lasan nigba pupọ a ma gbe ọkan awọn ọdọ soke, a ma fun wọn ni okun: nitori nwọn ko le ṣai ma gba, ki nwọn si ni ifẹ fun ẹniti o ba ba jẹ enia tutu, akọni olotitọ ati oninu-rere enia. Ẹkan pere ni Chateaubriand ri Washington ri, iba eyi si jẹ iranlọwọ ati okun fun ni gbogbo ọjọ aiye rẹ.

Lẹhin ti o rohin ọrọ ti nwọn jumọ sọ pọ tan, o ni "Ki aiye to lala pe nwọn o mọ mi, Washington ti ku a ti fẹrẹ le gbagbe rẹ, Nigbati mo ba pade nko jamọ nkan. On wa ninu gbogbo ọla rẹ—Emi wa ni kọrọgun ti ẹnikan ko mọ mi. Ko daju pe o tilẹ ranti orukọ mi ni ọjọ kan ṣulẹ. Ṣugbọn ayọ ni fun mi pe o tilẹ ṣi oju rẹ wo mi. Eyi fun mi ni okun ni gbogbo ọjọ aiye mi. Ire wa ninu ki ẹni nla tilẹ ṣiju wo ni lasan."

Nigbati Niebuhr ku, ọrẹ rẹ Frederick Perthes sọ nipa rẹ pe: "Ọgba ni ẹni nla! ẹkun awon enia buburu ati enia lasan, o un ati opo fun awon ẹni rere ati olotitọ, ọrẹ ati oluranlọwọ awọn ọdọ."

Perthes tun sọ nibomiran pe: "O dara fun ẹniti o nja ijakadi ki o fi awọn enia ti o mọ ja d radara sogba yi ara rẹ da nigbakugba; ero buburu a salọ nigbati oju ba nwo aworan ẹ iti bi o ba ṣe a nri loju koroju, oju a ti ni lati ro iru ero bẹ."

Ọkọnrin kan ti o jẹ Catholic ti ima ya ni ni owo ele, nigbati o ba fẹ ṣe eru tabi o ba fẹ rẹ enia jẹ, a da aṣọ bo ere ẹni mimọ ti o gbe sile loju. Bẹ na ni Hazlitt sọ nipa ti aworan arẹwa obinrin kan pe o dabi ẹnipe enia ko le hu iwa aidara kan ti o ba nwo aworan yi.

Talaka obinrin ara Germany kan tọka si aworan Luther (*the great Reformer*), eyiti o fi kọ si ara ogiri ninu ile aharamọ ti o ngbe, o ni "bi enia ba nwo oju ọkọnrin na, ẹni rere, a ṣe oluwatẹ ni ire."

Ani aworan enia ti o ba jẹ ọmọluwabi tabi ẹni rere, ti a fi kọ sara ogiri ninu ile, duro ni iduro bi ẹni ri ọrẹ ẹni. Eyi a mu

ni tubọ mọ oluwarẹ ju bi a ti mọ lọ. Ti a ba nwo oju rẹ a dabi ẹnipe enia ti o sunmọ si girigiri ni.

Eyi a jẹ itakun ti o so wa pọ mọ enia ti o ni iwa rere ti o ga ju tiwa lọ. A le ma le ṣe to ti ẹniti a gbe kalẹ niwaju wa na, ṣugbọn aworan rẹ ti a nwo nigbakugba bi ẹnipe a nri on papa, a ṣe iranlọwọ fun wa, a si fun wa ni okun de aye kan.

Fox a ma yangan ire ati apẹrẹ iwa ati ọrọ Burke ṣe on. O sọ ni ọjọ kan nipa rẹ pe. "bi on ba ko gbogbo ọgbọn ti a fi nṣe ilu, eyiti on kọ ninu iwe jọ, ti on ba ko gbogbo ẹkọ imọ ati gbogbo ẹkọ ti a kọ on nipa bi aiye ti ri ati bi a ti nṣe aiye, bi on ba pa gbogbo iwẹnyi pọ ti on ko wọn sori iwọn lapa kan; ti on ba si wa ko gbogbo ọgbọn ti on kọ ninu ọrọ ati ẹkọ ti Mr. Burke kọ on si ori iwọn lapa keji, ti Burke ni yio tẹ iwọn."

Professor Tyndall sọ pe biba Faraday ṣe ọrẹ pọ jẹ "okun ati agbara." Lẹhin igbati o ti ọdọ rẹ bọ ni alẹ ọjọ kan, Tyndall kọ ọrọ wọnyi silẹ: "Iṣẹ rẹ—iwe ti okọ—mu ni gba fun, ṣugbọn biba on papa lo pọ a mu ifẹ ẹni gbona, a ru ifẹ ẹni soke. Laisî tabitabi ọkọnrin pa ni. Mo fẹran agbara, ṣugbọn mo fẹ ma ranti apẹrẹ adapọ agbara pẹlu iwa pẹlẹ, ainifuja ati iwa tutu eyiti Fareday ni."

Awọn enia ti o tilẹ jẹ enia tutu jn ni agbara lati tun iwa awọn ẹlomiran ṣe lọna rere. Bayi ni a ri i pe iwa Dorothy aburo Wordsworth ni agbara lori iwa ẹgbọn rẹ ni gbogbo ọjọ aiye rẹ. O sọ pe ọpẹ aburo on lara on nigbati on wa ni ọmọde ati nigbati on dagba. Bi o tilẹ jẹ pe on gba ọdun meji lọwọ rẹ, sibẹ iwa ifẹni ati iwa tutu ti o ni ni o tubọ kọ on ni iwa, on ni o si mu on fẹran arofọ orin: "O fun mi ni oju, o fun mi ni eti. iwọn lala ati ẹru ti o ba ara de: ọkan ti iṣe orisun omije didun on ifẹ, ọgbọn ati ayọ."

Bayi ni a ri i pe awọn eniwa tutu nipa ifẹ ati ọgbọn wọn ni agbara lati tun iwa awọn ẹniti yio ṣe iṣẹ rere ni aiye lẹhin ọla ṣe.

Sir William Napier ka ti ọna iwa ti on mu lati ilẹ wa si ti pe, lọna kini, ti ọna ti iya rẹ kọ nigbati o wa ni ẹmọde; ati lẹhin eyi nigbati on di ọkọnrin, si ti apẹrẹ iwa rere ọgagun rẹ, Sir John Moore. Lati ilẹ wa ni Moore ti ṣe akiyesi awọn iwa rere ti ọdọmọkọnrin ọga awọn agbẹbọn yi ni o si jẹ ọkan ninu awọn ti Balogun na sọrọ iwuri yi fun ni Corrunna, "Ẹ kare, ẹnyin ọga awọn aghẹbọn mi *(Majors)*"! Nigbati o nkọwe ṣọwọ si iya rẹ ni ile, ti o nrohin Moore ninu ọla rẹ pẹlu awọn iba awọn enia ti o wa labẹ rẹ, o ni "Nibo ni a o ti ko iru ọba bi rẹ." Ifẹ ti o ni fun ọga rẹ ni o mu kọ iwe 'Itan Ogun Peninsular', eyiti gbogbo aiye ndupẹ lọwọ rẹ fun loni. Ṣugbọn ọrẹ rẹ kan Ologbe Lord Langdale ni o gba ni iyanju lati kọ iwe yi ni ọjọ kan bi awọn mejeji ti jumọ nrin lọ ni papa nibiti Belgravia wa nisisiyi. O ni "Lord Langdale ni o kọkọ fi ero na si mi lọkan."

Ni ti Sir William Napier papa, otitọ ni opitan rẹ sọ nigbati o wipe "ko si ẹda kan ti o jẹ enia ti o ni ero, ti o ba sunmọ, ti ko ni mọ pe ọlọgbọn enia ni."

*Translated by*

Adeyinka Ajagbe-Ọsa

---

***OLUSAKIN'S COLUMN.***

---

**St. Paul's Church, Idi Oro.**

On Sunday morning the 15th instant, it is understood that just by the time the Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi was getting ready to go to Idi Oro and Iṣagatẹdo Church to take an appointment there, the news of the death of his cousin—a female—reached him at the Parsonage, but with the usual christian fortitude characteristic of him, he fulfilled his engagement and preached a very touching and impressive sermon to the congregation at Idi Oro. Mr. E. W. M. George read a portion of the prayers, the lesson being read by Mr. D. A Bright. The Lord's Supper was administered

In connection with the bereavement we tender our heartfelt sympathy to the Venerable Archdeacon and Mrs. Ogunbiyi and all the relatives of the deceased.

**On Leave.**

Mr. W. A. Akiyẹmi, Assistant Storekeeper, Nigerian Railway Stores Department, Port Harcourt, is on one and half month's leave, as from the 24th March, 1928. Mr. Akiyẹmi arrived Lagos on the 1st April to spend the vacation with his family.

---

Mr. Samuel S. Oshinde, 2nd Class Pressman, Railway Press, Ebute-Mẹtta, is on a month's leave, as from the

10th April, 1928. Mr. Oshinde proposes to spend some portion of his leave at Shagamu via Ikorodu.

**Arrival.**

By the "T.S.M.V. Accra" which arrived this port on Thursday, the 12th instant, Mr. Mobọlaji Akinshemọyin, B.A., Barrister-at-Law, returned to Lagos, from Accra, Gold Coast, whither he had gone on health trip.

**Wesleyan Ereko Church.**

At Wesleyan Ereko Church, on Sunday morning, the 15th instant, Mr. C. W. Faulkner-Shaw, Chief Clerk, General Manager's Office, Ebute-Metta, occupied the Pulpit and preached an interesting sermon.

His text from Phillipians, chapter 3, verse 10.

**Is it a fact ?**

The dedication of the new Church of St. Jude's, Ebute Metta, we learn is to take place on Saturday, the 12th of May next, at 3.30 p.m.

**Conference of Friendly Society.**

A Thanksgiving Service of the Conference of Friendly Society consisting of Foresters, Odd Fellows and Shepherds will be held tomorrow at St. Paul's Church, Breadfruit, the 22nd April, 1928, at 4 p.m., precisely. All are cordially invited.

**Christening.**

The Christening ceremony of the Infant child Theodosius Bafunmilayo Olușola, son of Mr. & Mrs Jacob K. Fakeyẹ took place at C.M.S. Church, Ișagatẹdo, via Mushin, on Sunday, the 15th April, 1928, at 11 a.m.

The Sponsors were Mr. E. W. M. George and Mr. & Mrs. D. A. Bright. The Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, L.th., officiated.

Immediately after the ceremony, the guests retired to Teacher Fakeyẹ's residence, where refreshments were served. A ki nyin ẹ ku inawo, ki Oluwa ko da ọmọ na si.

**Marriage**

A fashionable marriage between Mr. James Akinwunmi Phillips and Sarah Ibidunni Daniels, took place at Seraphic Society, 21, Martins Street, Lagos, on Tuesday, the 17th April, 1928, at 6.35 p.m. Mr. Moses Orimọlade (the Founder) officiated.

No Wedding Ring allowed for the Bride owing to the system adopted by the Seraphim.

We wish Mr. & Mrs. James A. Phillips happy home and all connubial bliss.

To Messrs. Henry Babalọla and H. Akinọla Phillips, Ẹ ku inawo, Iyawo a ș'anfani.

**His Excellency the Governor.**

His Excellency the Governor and Lady Thomson and His Excellency's Personal Staff arrived Lagos on Wednesday last, from tour of inspection.

**Imprisonment for European.**

Mr. E. W. Brown of the West African Lighterage and Transport Co., was fined £3 and one month's imprisonment on Monday last for 1. Riding motor cycle without licence; 2. Riding to common danger; 3. Wounding Mr. Ayitey Adjin; 4. Wounding Mr. Hoffman. It is said that the defendant's attitude towards witnesses, *i.e.*, those whom he had wounded was rather over-bearing and such unmannerly terms as niggers, black monkeys, etc., were, it is alleged, freely used. Apparently to bring him back to ordinary civil language and a full realisation of things mundane, he was fined £3 on three of the counts and one month's imprisonment without the option of a fine. The sentence came as a surprise to him. Through the intercession of his employers a barrister was allowed to plead successfully for mercy and the sentence was commuted to a fine.—*The Gold Coast Independent*, 7/4/28.

**Death of Rev. S. P. Johnson.**

It is with deep regret that we announce the death of Rev. Simeon Peter Johnson, an aged and retired Methodist Minister of the Wesleyan, which sad event occurred at his residence, 10, Shitta Street, Lagos, at about 2 a.m. on Monday, the 16th April, 1928.

The funeral service took place the same afternoon at Wesleyan Trinity Church, Tinubu, before a large concourse of people. Rev. Superintendent Olliver J. Griffin, officiated, assisted by Revs. A. N. Cole, E. E. Williams, M.A., J. C. Cole, B.A., D. A. Tekoe, T. J. Henry and M. O. Dada.

The interment was in his family vault at Ajẹle Cemetery.

Rev. S. P. Johnson died at the age of 78.

To Mr. and Mrs. Tobiah Johnson, Mr. and Mrs. Akinwunmi Johnson, Rev. and Mrs. Evan Williams, Mr. and Mrs. C. B. Olumuyiwa and the relatives of the deceased.—Sympathy.

May he rest in peace.

OLUSAKIN.

INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oșupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yọ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le șẹșẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Șango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o ma electric jẹ.

Oriși meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Șabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miràn, ẹ mase gbẹhin ki ẹ to ranșẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

# Iyin Oluwa Medicine Store

**K. B. SAVAGE,**

*CHEMIST & DRUGGIST.*

STOCK :—

## YARO

***The oldest and best Infants Preservative 1/6d & 3/-.***

## WIRELESS FEMALE PILLS

***The scientific preparation for all monthly Disorders peculiar to Females. 4/6d per bottle.***

## KADUNA BALM

(IPARA AWO'GBA ARUN).

***Can be applied in 100 different ways !!! 1/-.***

## Write or call at :—

88, Broad Street, Lagos,

6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

109, Griffith Street, Ebute-Metta.

**Watch this space every week.**

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strenegth) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### REMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ęda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.

41, Offin Road, Lagos.

*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ęda, Aran, Oyun ti o ba fę bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.

Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WOND F I U BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq

41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ĘJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ęda ti o ba gbo, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ęsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.!

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—:o:—

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọm
ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to k
si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi a
awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si
ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


[Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 2d, Market Street, Lagos, and Published
Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.